GO PLACES IN A HILLMAN FROM ARAB BROS MOTORS LTD.

IROHIN IMOLE

MOTTO: IMOLE DE, OKUNKUN PARADA.

For Sale

An Opel rekord Car Driving by the owner price £120 or nearest

apply to:-

MODUPE PRESS
16, Bamgbose Street
Lagos. Phone: 21985

VOL. V No. 205 MONDAY JULY 31 — AUGUST 6 1961 KOBO KAN (1d)

# Omode kan lu Iya re pa, ni-toripe o ko lati fun li onje

**ABEOKUTA:- FUN MI NI ONJE, NKO FUN O NI ONJE LO DA EDEKOYEDE SILE LARIN OMODEKUNRIN AGBE KAN PELU IYA RE DEIPO TI OMO NA FI IBINU LU IYA RE NI ILUKI-LU TOBE TI IYA RE NA FI DI ERO AJIRAN,**

Awon olopa ki omodekunrin na mole, nwon si fi sun esun apania, omode na koju eni odun medogbon lo. oruko omo ti o lu iya re pa na nje Ayinde Bandele ti Abule Elegba ni agbegbe Egba Odeda, oruko iya re ti o lupa na nje Abisoye Tejumola. Bi a ti gbo wipe oro na lo niyi, Ebi lo npa Ayinde ti ofi to iya re wa wipe ki o fun on ni onje sugbon iya na ko wipe rara on ko ni fun Ayinde li onje. Eyi mu ki Ayinde binu, dide si iya re, o si lu u ni ilukulu tobe ti iya na fi ku.

Ogbeni kan ti o nje Shodimu Akintan so pe on ni egbon iya to bi Ayinde. Sugbon nigbati o pada dele, o ba Abisoye ti ise iya Ayinde ti o nyira nile, ti o si nke ibosi wipe Ayinde omo ti on bi lo mpa on ku lo yio. Nigbana si on wa ranse lo pe Olopa, Sugbon ki awon olopa to de Abisoye ti ku. Ni nwon ba gbe oku na lo si Abe okuta lati lo juri re, ki nwon mo kini ohun ti o fa iku re, Ejo na si mbe ni Kotu, nwon koiti pari re bi a ba ti gbo oro na si, e o ma gbo.

### HAUSA KAN LAGEGE LO PA ENIA NI IBADAN

IBADAN: Obinrin Hausa kan ti nwon npe ni Abu Jebba ni Agege lo si Ibadan, oro kan se bi oro larin Abu Jebba ati Okunrin Hausa kan ti nwon npe ni Garuba Dangambo ti o ngbe adugbo Sabongeri nilu Ibadan. Abu Jebba ko beni, beji, o gbe igo ofifo ti oti bia, o lamo Dangambo lori, oyi gbe Gambo, o si subu lule. Agbo wipe Abu Jebba tun sare mo, o tun mu afoku igo na, otun la mo Gambo lori, A koiti gbo wipe oro na si loju, awon olopa si nwadi oro na lowo.

## Akiyesi Pataki

A FI EYI SE IKEDE FUN GBOGBO ENYIN OKAWE IROHIN IMOLE KAKIRI AGBAIYE.

PE LATI OJO K E R I N (4th September) OSU KESAN ODUN YI, OJU EWE IROHIN IMOLE YIO DI MEFA TABI JU BE LO, SUGBON KO NI JE OJU EWE MERIN MO.

BAKANNA NI OWO TITA RE YIO JE KOBO MEJI (2d) PERE.

**Olotu**

# Iwadi oro nipa National Bank tun ye fun ojo meje

EKO:- A gbo wipe a w o n Igbimo Senate tun fi ase si pe dandan aya fi bi nwon ba se iwadi nipa National Bank nitoto, nwon bere iwadi na ni agogo mesan abo Nigbati o di ni agogo mokanla abo ni Adajo Onyeama ranse lo ba won nibiti nwon gbe nse iwadi na wipe, ki nwon da iwadi na duro fun ojo meje gba ko.



OLOLA VAHE BAIRAMIAN

Adajo Onyeama wa nibiti Oloye Rotimi Williams, gbe ntoka si ofin ti o so wipe ki nwon da iwadi na duro ni akoko ti nwon nse iwadi oro Bank na lowo. Nigbati onise de ti o si jise fun Oluwadi oro wipe, Adajo Onyeama ni ki o da iwadi oro na duro fun ojo meje titi a o fi yanju oro esun ti nwon fi sun niwaju on yi, lati owo Oloye Bayo Doherty ti ise Olotu National Bank, lati le fi da oro iwadi na duro titi nwon o fi gbo oro enu on.

Ibe ni Oloye Rotimi Williams Q. C. ti na ofin yo wipe, bi nwon ti se gbe oro iwadi na dide lo di si ofin ilo wa Ijoba Alapapose tabi Igbimo ilu ko lase kan lati se ofin le ori oro iwadi na. Ni odun 1957 ni Ijoba Alapapose ti lase lati se be, sugbon ofin na ti yi pada ninu odun 1959 wipe ofin kan wa ti o fun prime Minister lase se iwadi, ko si ofin ti o wi be, Ijoba ni kan lo lagbara pe ki nwon se iwadi, ko nse Ijoba Alapapose.

# ORO PATAKI FUN AWON OBINRIN

Lati Qwọ:- IYAFIN ALAKE (Eko)

MO KI GBOGBO Ẹnyin Obinrin ọlẹgbẹ mi, ati gbo-Gbo Ọnkawe Irohin Imọlẹ kakiri Agbaiye, Ajinde Ara yio ma jẹ fun gbogbo wa o, gẹgẹ bi mo ti ṣe ileri pe emi ki yio fi yin silẹ lai ko ma gba ẹnyin Obinrin ni imọran tabi ọrọ iṣiti.

Inu mi dun pupọ nigbati mo ri iwe yin, ṣugbọn ohun ti mo fẹ fi ye yin, nipe ninu awọn ti mo ri we wọn yi, awọn kan wa ti o jẹ pe wọn kọ bere ti wọn ti emi ko si ri ka, Nitorina ki ẹ jọwọ ki ẹ ma kọ ọrọ yin ki o ma yanju ki ẹ to ma fi ranṣẹ simi, eyi jẹ ohun ti o fa ti emi ko si ti fẹ dahun ibere ti mo ti ri gba. Ẹ jọwọ ẹnyin onibere ẹ ma se binu o. Ọrọ mi ti ọsẹ yi yio jẹ lori ẹnyin Obi tabi ẹnyin Alagbato, mo bẹ ẹnyin obi tabi Alagbatọ ki ẹ ma mo ju to awọn ọmọ yin obinrin, mo bẹ yin pupọ, ẹ ma mọ bi wọn ti nlọ si si ninu Ẹkọ wọn nipa pe ki ẹ ma yẹ iwe wọn wo, ẹnyin obi ti ẹ ko ba si mo iwe, ẹ ma fi han awọn ẹniti o ba mọ we ti o ba wa ninu ile yin. Ti awọn ọmọ yin ba si nlọ sile Ẹkọ, ẹ ma wo apo wọn wo, ki ẹ si ma ri pe wọn ko fi asọ kan sinu apo mọ ju we lọ, ki wọn to lọ, nitori awọn ọmọ wa lsinyin ti gbọn ọgbọn buruku nipa pe ki wọn ma sa nile ẹkọ, ki wọn wọ ẹ u miran nigbati wọn ba ti bọ ẹwu ile ẹkọ wọn silẹ, eyi jẹ ohun ti o fa pe ki ọmọ ọdun mejila ma loyun apapa dodo, mo bẹ yin ẹ ma ba wọn sọrọ nipa ifẹ, ṣugbọn ohun ti ẹ o ma sọ fun wọn nipe ẹ ko ni ki wọn ma ni ọkọ. ṣugbọn ki wọn mura si ẹkọ wọn na ki wọn kawe tan ki wọn to ma tẹle ọkunrin, ki ẹ si ma sọ fun wọn pe ki wọn ma ni ifẹ ọkunrin ju owo lọ nipa eyi nigbati wọn ba ni fẹ ọkunrin ti wọn ko gba owo wọn, ko ni le fi ohun kohun lọ wọn nipa biba wọn lo pọ ki wọn si ye ma lọ sọdọ ọkunrin ayafi ti wọn ba pade ni le ẹgbẹ (Club) tabi lode ki wọn sọrọ diẹ ki onikaluku si gba ọna ile tirẹ lọ, ki ẹ si ma sọ si wọn leti nipa ohun ti o tọ yatọ si ohun ti ko tọ ki ọmọ binrin ma ṣe. ki ẹ si ma tẹ wọn lọrun nipa pe ki ẹ ma ṣe ohun ti wọn ba bere lọwọ yin fun wọn, ti ẹ ba ṣe bayi eyi yio mu wọn ronu piwada, wọn yio si mura si ẹkọ wọn.

Nitori ki ṣe pe ki a ma na ọmọ ni o ni ki o gbọn tabi ki o ma tẹle ọkunrin. Ṣugbọn ohun ti a le ṣe ti o le mu wọn ronu piwada ni lati ma ba wọn ṣọrọ iṣiti tabi lati ma fi awọn obinrin ẹlẹgbẹ wọn ti o wa ni po giga ṣe apejuwe fun wọn, ki a si ma bẹ wọn ni kọrọ ti a ba ṣe eleyi yio mu ronu piwada lati ye ma rin iriin kunrin.

Ẹnyin Obi ẹ ma mọ aṣọ ti ẹ ba ra fun awọn ọmọ yin dada, ẹ ye ma jẹki wọn mu aṣọ miran wọle yin, ki ẹ si ma mọ iye ti ẹ ba fun wọn yatọ si eyiti ẹ ba nri lọwọ wọn' ki ẹ si ye gba wọn laye lati lọ sode lẹhin agogo mẹjọ alẹ. ki ẹ si ma ri pe wọn kawe wọn nile lojojumọ.

Njẹ emi ọmọ Wu'emọtu erele, emi ni ọmọ bi mo ṣiṣẹ ngo lowo bi ini ko ṣiṣe ngo lowo, Ajila ni baba mi, ṣiṣẹ olowo ọmọ ile Agbọrun, A ki sun lowo Ọmọ Igbo-ọra, Oiburuku kiṣẹ temi, o digba ka fi rere pade o.


AWON IWE KO SE MANI
IWE EGBOGI FUN ONIRURU IWOSAN;
IWE ADURA IṢEGUN AWON AJẸ;
IWE IFA AGBON-NIREGUN, IWE ITUMO ALA PẸLU IWADI NKAN;
IWE LILO ATI AGBARA PSALMU;
★★★ IWE ADURA TETE DA MI LOHUN;
★★★ IWE ITAN ABALAIYE ATI TI IṢEDALE.

KOWE FUN IWE-ITAJA:-
OLOTU BOX 104
EBUTE METTA, NIGERIA.



For all your Printing Reguirements

Invitations, Programmes, Hand bills, Pamphlets, Advertising Material and all Commercial Jobbing

Send your Jobs to :-
MODUPE PRINTING PRESS.
16, Bamgbose Street, Lagos. Phone: 21985

Where Quality Print, costs less.




